# IFẸ ỌLỌRUN

**1 Kọrinti 13:1-13**

**ẸKỌ 355 --- FUN AGBA**

**KỌSORI: “Ati bori gbogbo nkan wọnyi, ẹ gbé ifẹ wọ̀, ti iṣe àmure iwa pipé” (Kolosse 3:14).**

**I Ifẹni -- Eyi ti i ṣe Ifẹ Ọlọrun**

1 Ifẹ ni kókó ati akopọ ẹ̀sìn otitọ. Ẹbun-ahọn, isọtẹlẹ̀, imọ̀, igbagbọ, iṣoore ati itara fun otitọ -- iwọnyi kò mu igbala wá, 1 Kọrinti 13:1-3; Deuteronomi 6:5; Lefitiku 19:18; Deuteronomi 10;12, 13; Marku 12:28-31; Luku 10:25-28

2 A ṣe alaye awọn eso rere ti ó wà ninu ifẹni tabi Ifẹ Ọlọrun, 1 Kọrinti 13:4-7; Owe 10:12; 1 Peteru 4:8; 2 Johannu 5

3 Isọtẹlẹ, ẹbun-ahọn, ati imọ yoo dopin, ṣugbọn ifẹ Ọlọrun wa titi lai, 1 Kọrinti 13:8-10; Kolosse 3:14

4 A ṣe apejuwe ipo aipe ti ọmọ eniyan wà, 1 Kọrinti 13:11, 12; 2 Kọrinti 3:18; 5:7; 1 Johannu 3:2

5 Ifẹ ni ohun ti o tobi ju lọ, 1 Kọrinti 13:13; Matteu 5:44; Romu 13:10; Johannu 13:34; 15:9, 13, 17; Heberu 13:1; 1 Johannu 3:1; 4:7-12, 17-19

## ALAYE

### Ijọ Kọrinti

Oṣu mejidinlogun ni Paulu lò ni Kọrinti, ti o fi n waasu fun awọn ara Kọrinti. A ti dá Ijọ ti o lagbara silẹ; ṣugbọn lẹyin ti Paulu kuro nibẹ, iyapa ati ẹkọ ìṣìnà ti yọ wọ aarin wọn. Awọn Hellene fẹran ki wọn maa ṣe apọnle eniyan. Paulu kọ Episteli yii lati ṣe atunṣe awọn nnkan wọnyii. Ori ikẹtala iwe yii jẹ iyanu, a si ka a si ọ̀kan ninu awọn ti o ṣe pataki ju lọ ninu Bibeli. O yẹ ki ẹni kọọkan le kọọ sori.

Ẹni kan ti sọ pe, “Ifẹ ni aworan Ọlọrun gan an ninu ọkan; nitori pe ifẹ ni Ọlọrun. Nipa igbagbọ́ ni a maa n ri nnkan gbà lọwọ Ẹlẹda wa; nipa ireti a maa n foju sọna fun ọjọ iwaju ati ayeraye; ṣugbọn nipa ifẹ ni a fi n jọ Ọlọrun; ati pe nipa ifẹ nikan ni a o fi ni ẹtọ lati jẹ igbadun Ọrun ti a o si fi jẹ ọ̀kan pẹlu Rẹ̀ titi ayeraye.” Ifẹ́ ni akoja ofin. Ofin kò lagbara lati yi igbesi-ayé eniyan pada, ṣugbọn Kristi, ti i ṣe Ifẹ́ di eniyan, ṣe e!

### Ibi Titun

Johannu Apọsteli sọ gbangba pe “Ifẹ ni Ọlọrun; ẹniti o ba si ngbé ninu ifẹ o ngbé inu Ọlọrun, ati Ọlọrun ninu rẹ̀.” A fun wa ni iwọn ifẹ Ọlọrun , nipa ododo Jesu Kristi nigba ti a ba tun wa bi. Iyatọ wa ninu ifẹ Ọlọrun ati ifẹ ti eniyan. A bi wa sinu ayé yii pẹlu ifẹ ninu wa irú eyi ti o mu ki awọn obi fẹran awọn ọmọ wọn, ati ifẹ̀ diẹ tabi pupọ ti a ni si ẹda eniyan. Awọn ẹranko paapaa ni ifẹ si awọn ọmọ wọn. Ṣugbọn ẹ̀ṣẹ dapọ mọ ifẹ yii ninu ọkàn eniyan, eyi ni ẹ̀ṣẹ ti a gbìn sibẹ nigba ti eniyan ṣaigbọran si Ọlọrun ti o si ṣubu kuro ninu ifẹ pipe ati ipo ailẹṣẹ. Ki eniyan to tun le pada di aworan Ọlọrun, a gbọdọ yi i pada. A gbọdọ sọọ di ẹda titun. Jesu pe iyipada yii ni ibi titun. Awọn eniyan ti gbiyanju lati fi ohun pupọ dipo ibi-titun yii. Wọn ti dán ẹkọ wò, wọn dán ṣiṣe atunṣe nnkan wò, didarapọ mọ ijọ kikọnfaaamu, oore ṣiṣe, ṣiṣe iranwọ fun talaka ati alaini, lati fi dipo iyipada ọkan. Jesu wi pe ẹni ti o “ba gbà ibomiran gùn oke, on na li olè ati ọlọṣà” (Johannu 10:1). Asán ni gbogbo ilakaka eniyan lati de Ọrun lọna miiran yatọ si ọna ibi titun. “Bikoṣepe a tún enia bi, on kò le ri ijọba Ọlọrun” (Johannu 3:3).

### Isọdimimọ́

Bi o ti ṣe pe ifẹ n wọ inu ọkàn nigba ti a ba tun wa bi, o ṣe e ṣe ki “a mu ifẹ ti o wà ninu wa pé” (1 Johannu 4:17), nipa iriri ti o tun jinlẹ si i ti a n pe ni isọdimimọ́, iṣẹ oore-ọfẹ keji ti o daju, ti o n ṣẹlẹ lẹsẹ kan naa. “Ẹnikẹni ti o ba npa ofin rẹ̀ mọ́, lara rẹ̀ li a gbé mu ifẹ Ọlọrun pe nitõtọ” (1 Johannu 2:5). “Ifẹ pipe” jẹ́ orukọ miiran fun “iwa mimọ́,” “pipé Onigbagbọ́,” tabi isọdimimọ́,” eyi si maa n ṣe e ṣe nigba ti a ba tu gbongbo ẹ̀ṣẹ kuro ninu ọkàn nipa ibuwọn Ẹjẹ Jesu Kristi. “Kristi si ti fẹran ijọ ti o si fi ara rẹ̀ fun u; ki on ki o le sọ ọ di mimọ́ lẹhin ti a ti fi ọrọ wẹ ẹ mọ́ ninu agbada omi. Ki on ki o le mu u wá sọdọ ara rẹ̀ bi ijọ ti o li ogo, li aini abawọn, tabi alẽbu kan, tabi iru nkan bawọnni; ṣugbọn ki o le jẹ mimọ́ ati alaini àbuku” (Efesu 5:25-27).

### Ahọ́n

Ọpọlọpọ oniwaasu olohun iyọ̀ ni o wà. Ni ọ̀pọlọpọ igba ni a maa n gbọ́ irú ọrọ bayii “Gẹẹsi yọ̀ lẹnu rẹ̀.” Ṣugbọn bi ifẹ Ọlọrun kò ba kún ọkàn oniwaasu naa, gbogbo aṣaro ọ̀rọ rẹ̀ daradara, ati gbogbo gẹẹsi rẹ̀ to gbadun dabi idẹ ti n dún ati bi kimbali olohun gooro. Pupọ awọn ọkàn ti ebi n pa lo ti jade ni ile isin nlá nlá lai ni itẹlọrun nitori pe awọn oniwaasu kuna lati ni ohun kan ti o ṣe pataki jù lọ -- Ifẹ Ọlọrun.

**Igbagbọ́**

A sọ fun ni ninu Heberu Ori Kọkanla pe “Igbagbọ́ ni idaniloju ohun ti a nreti, ijẹri ohun ti a kò ri”, ati pe nipa igbagbọ ni a ṣẹgun ilẹọba, a di awọn kiniun ni ẹnu, a si ji awọn oku dide laaye. Jesu yin obinrin ara Sirofenikia fun igbagbọ́ rẹ̀, ẹni ti o fi irẹlẹ bẹbẹ fun iwosan ọmọbinrin rẹ: Jesu wi pe, “Obirin yi, igbagbọ́ nla ni tirẹ.” Ẹ jẹ ki a ranti igbagbọ́ ti balogun-ọrun paapaa, ẹni ti o bẹbẹ fun iwosan ọmọ-ọdọ rẹ̀. Jesu sọ pe Oun ko i ti i ri irú igbagbọ́ nla bi eyi ni Israẹli. Ohun iyanu nla pupọ ni o ti ṣẹlẹ nipa igbagbọ́. Ṣugbọn Paulu fi hàn pe bi kò ṣe pe igbagbọ́ ba dapọ mọ́ ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn, ki yoo ṣe ọkàn ni ire kankan. Igbagbọ nikan ki yoo tó lati ṣi ilẹkun perli Ọrun fún ni.

**Okiki**

Ọpọlọpọ awọn ọlọrọ ni o ti yọọda owo wọn fun iṣẹ oore, wọn fi owo ṣe iranwọ fun ọ̀pọ ile-ẹkọ giga, ọ̀pọ ile itọju alaisàn ati irú awọn ibi bẹẹ bẹẹ. Awọn ẹlomiran tilẹ ti lọ jinna ju bẹẹ to bẹẹ ti wọn ti fi ara wọn fun igbekalẹ ti wọn pọnle. Ṣugbọn Kọrinti kin-in-ni ori ikẹtala fi ye ni gbangba pe bi kò ṣe pe a bá ni ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn, gbogbo awọn nnkan wọnyii ki yoo fun wa ni ère kankan. Orukọ wa, okiki wa ati ohun gbogbo ti a ni yoo parẹ bi ọjọ ti n lọ. Ẹkọ ti o ga ju lọ, imọ iṣẹ-ọna ati oyè-ẹkọ ti o ga ju lọ, imọ-ijinlẹ ati imọ awari ọgbọ́n, ṣiṣẹ ohun titun ti igbalode kò le mu kekere ninu ifẹ Ọlọrun wọ ọkàn ẹnikẹni. Ẹbun ọfẹ Ọlọrun ni ti a fi Ẹjẹ Ọmọ Rẹ̀, Jesu rà; nipa gbigba Jesu Kristi Oluwa wa gbọ́ ni a si le fi ni i.

**Awọn Iṣe Ifẹ**

Paulu ṣe alaye ifẹ, o fọ́ ọ si wẹ́wẹ́, o si sọ fun ni ohun ti ifẹ i ṣe gan an. Ifẹ́ a maa ṣoore, a si maa mú suuru. Ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn a maa mu ki eniyan le fara mọ́ ofin iṣoore. Itumọ eyi ni pe ki i ṣe oniwa-tutu ati onifarada nikan, ṣugbọn oun jẹ́ olooótọ si awọn ọkàn wọnni ti wọn jẹ́ alaiṣootọ si ara wọn. Ọpọlọpọ eniyan ni o jẹ́ alaiṣootọ si ara wọn, wọn a si maa gbiyanju lati bo aiṣootọ yii mọlẹ ninu ọkàn wọn. Wọn n fẹ ẹni kan ti o ṣe oninuure ti o si gbọ́n lati ṣe iranlọwọ fun wọn lati tú aṣiiri ohun ti wọn n bò ti o si le mu wọn padanu ẹmi wọn nikẹyin bi wọn kò ba ronupiwada. Inu-rere jẹ́ iwa-ọrun ti a ṣiṣẹ rẹ̀ ninu ọkàn ti o si maa n jẹ yọ ninu ọ̀rọ ẹnu.

Ẹni ti o ba ni ifẹ ki i ba arakunrin rẹ̀ jẹ́. O ṣe e ṣe ki o ba a wi, ki o si kilọ fun un, ṣugbọn labẹ ibawi nì ni ofin iṣeun wà lati bu ororo si i. Jẹjẹ ni ifẹ, o si ni ẹmi ibanikẹdun ninu ara rẹ̀, a maa ṣeun a si maa ran awọn ẹlomiran lọwọ. Ki i maa dá ijọgbọn silẹ. Ifẹ a maa mu ki eniyan fẹ lati fi ti awọn ẹlomiran ṣiwaju. Ifẹ ki i ṣe ainitẹlọrun si ayọ̀ ati igbega awọn ẹlomiran. Ki i gbé ara rẹ̀ siwaju, ki i si fẹ ki a ṣe afiyesi tabi ki a yin oun. Ifẹ ki i yara ṣe idajọ tabi yara bá awọn ẹlomiran wi. Ifẹ ki i fẹ fi hàn bi oun ti ṣe pataki tó. Irẹlẹ tootọ a maa dide lati inu ẹ̀kún ibukun Ọlọrun ninu ọkàn.

Awọn eniyan, tabi ohunkohun ti o wù ki o ṣẹlẹ, ki i mu ifẹ huwa lodi si ipo rẹ̀ ninu ayé. Ifẹ tootọ a maa mú ki ẹni ti o ba ni i ṣe irú ohun ti o kun fun ironu ti o tọ́ ti o si yẹ nipa ohunkohun ti o ba ṣẹlẹ. Ifẹ ki i maa wá ohun ti ara rẹ̀, ki i si i ni itẹlọrun bi kò ṣe ninu ire, irọrun ati igbala awọn ẹlomiran. Ninu otitọ nikan ṣoṣo ni o maa n yọ̀. A maa farada ailera ati ikuna awọn ẹlomiran, a si maa gba eyi ti o dara ju lọ ti o ṣe e gbagbọ́ nipa eniyan, a maa ni ireti fun igbala ati ilọsiwaju awọn eniyan ni ibi gbogbo, a si maa fi ara da idanwo ati ipọnju pẹlu igboya. Kò si ẹni ti o le wa ni imurasilẹ tootọ fun ogo ayeraye bi kò ṣe pe ifẹ Ọlọrun yii ba jinlẹ gidigidi ninu ọkàn ati ẹmi ẹni naa.

**Ifẹni**

Ifẹ ki i yẹ lai. Isọtẹlẹ yoo dopin, ẹ̀bun-ahọ́n yoo dopin, imọ̀ yoo parẹ ṣugbọn ifẹ Ọlọrun yoo duro lailai. Ni orilẹ-ède okunkun Afirika nibi ti David Livingstone jẹ́ eniyan alawọ funfun kin-in-ni ti o kọkọ wọ inu awọn ilu ti o jinna si eti okun lọ, a sọ fun ni pe nigba ti a ba darukọ rà, oju awọn eniyan dudu wọnyi a maa fani mọra bi wọn ti n sọrọ nipa onisẹgun oninuure naa ti o ti wá si ilẹ wọn ni ọ̀pọ ọdún sẹyin. Wọn kò gbọ́ ède rẹ̀, ṣugbọn wọn mọ bi ifẹ ọkàn rẹ̀ ti tó si wọn. Bi a ba gba oore-ọfẹ kekere nì ti ifẹ Onigbagbọ sinu ọkàn wa, iṣẹ wa yoo yọri si rere. Kò si ohun ti o tobi ju eyi lọ ti a tun le di mú.

**Eyi ti o Tobi Ju Lọ**

Njẹ nisisiyii, igbagbọ́, ireti ati ifẹ n bẹ, ṣugbọn eyi ti o tobi ju ninu wọn ni ifẹ. “Lati ni ifẹ ọ̀pọlọpọ ni lati gbé igbesi-ayé itẹlọrun lọpọlọpọ, lati fẹran titi ayé, oun ni lati wà titi lai” ni iranṣẹ Ọlọrun kan wi. Nitori naa iye ainipẹkun so pọ̀ mọ́ ifẹ́.

Laisi igbagbọ́ kò ṣe e ṣe lati bá Ọlọrun rìn. Igbagbọ́ n mú wa sunmọ Ọlọrun, ati pe nipa igbagbọ́ ni a si fi n bá Ọlọrun rìn. O jẹ́ ọ̀kan ninu awọn ohun mẹta ti o tobi: Ireti lo maa n mu ọkàn fó, a si maa mu ni tẹ̀ siwaju. Ireti ni fifi igboya fi oju sọna fun ohun ti n bọ̀. Aṣibori wa ni ireti igbala. A maa n wọọ ni gbogbo igbà. Lai si ireti, ọkàn a ṣaisàn a si kú. Ni wakati iṣudẹ̀dẹ̀ paapaa ireti yoo dide fun iranwọ wa. Igbagbọ́ ati ireti ni a maa n mu rin àjo ayé yii já, ṣugbọn ifẹ ni yoo ba wa lọ si ayeraye. Eyi ti o tobi jù ninu wọn ni ifẹ!

**Ifẹ Ọlọrun bo ti dara to!**
**Alaini 'wọ̀n alagbara**
**Yoo wa titi ayeraye**
**Orin awọn mimọ́ at'angẹl."**

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni awọn ohun nla mẹta ti a fi wé ara wọn ninu ẹkọ yii?

2 Ṣe apejuwe igbagbọ́.

3 Ṣe apejuwe ireti.

4 Ṣe apejuwe ifẹni.

5 Sọ iyatọ ti o wa laaarin ifẹ eniyan ati ifẹ Ọlọrun.

6 Ki ni iwaasu tabi ẹri-jijẹ jọ bi ifẹ Ọlọrun kò ba si ninu ọkàn?

7 Ki ni n sọ eniyan di Onigbagbọ́ tootọ?

8 Darukọ diẹ ninu awọn eso ifẹ Ọlọrun.